# AYỌ̀ ONIGBAGBỌ́

**Filippi 3:1-3, 7-16, 20, 21; 4:1-13**

**ẸKỌ 406 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ẹ mã yọ̀ ninu Oluwa nigbagbogbo: mo si tún wi, Ẹ mã yọ̀" (Filippi 4:4).**

**I Awọn Ikilọ**

1 A kilọ fun awọn ará lati kiyesara lọdọ awọn ẹlẹsìn gẹgẹ bi igbekalẹ awọn Ju ati awọn ọnişẹ-buburu, Filippi 3:1, 2; 2 Peteru 2:1

2 Awọn ti a kọ nila nipa ti ẹmi a maa yọ̀ ninu Kristi Jesu, Filippi 3:3

**II Lilepa Lati Dabi Jesu**

1 Ifẹ ọkàn Paulu ni lati fi ohun gbogbo silẹ ki oun ba le şişẹ fun Oluwa Jesu Kristi, Filippi 3:7-9

2 Paulu fẹ şe alabapin iyà ati ajinde Oluwa, Filippi 3:10, 11; 2 Timoteu 2:12

3 O n lepa siwaju lati de giga oore-ọfẹ Ọlọrun, Filippi 3:12-14

4 O gbà wá niyanju lati rin yẹ si ipe ti a pè wá, Filippi 3:15, 16; Efesu 5:2

5 Ireti wa ni ipadabọ Oluwa, Filippi 3:20, 21

**III Ẹ Maa Yọ̀ Ninu Oluwa**

1 O paşẹ işọkan ati iranwọ fun awọn ara, Filippi 4:1-3; 1 Kọrinti 1:10

2 Ipo ti o ni ibukun fun wọn ni lati maa dupẹ ki wọn si maa yọ̀ ninu adura wọn, Filippi 4:4-6

3 Ọlọrun yoo pa awọn wọnni ti o gbọran si ikilọ wọnyii mọ́, Filippi 4:7; Isaiah 26:3

**IV A Ni Lati Şakoso Ero Ọkàn**

1 Onigbagbọ́ ni lati maa ronu nipa ohun ti o tọ́, Filippi 4:8, 9; 2 Kọrinti 10:4, 5

2 Paulu yọ̀ nitori o ti kọ́ lati maa gbẹkẹle Oluwa ninu ipokipo, Filippi 4:10-12

3 Agbára rẹ̀ ati işẹgun rẹ̀ n ti ọdọ Kristi wá, Filippi 4:13; Habakkuku 3:19

## ALAYE

### Ọkàn Paulu N Lepa Ohun Mimọ́

Ifẹ ti o leke ninu ọkàn Paulu ninu igbesi-ayé rẹ̀ ni lati de ibi Ajinde Kin-in-ni. O mọ̀ pe lati ni eyiini yoo jẹ́ ogo ti o pọju lọ fun gbogbo işẹ́ ati idanwo ti a pe e si lati rekọja. O ti ri iran iyanu ti o mu ki o sọ gbogbo ifẹ fun ilepa awọn ohun ti ayé nù. Ọpọlọpọ anfaani ti o ti ni ti o si n gbadun wọn şiwaju iyipada ọkàn rẹ̀ ni o ti kà si òfo nisisiyii. O kà wọn si ohun ti kò niyelori tobẹẹ ti wọn fi di ohun ẹgàn ati ohun ti kò yẹ fun iranti mọ́. Otitọ si ni eyiini ni igbesi-ayé gbogbo Onigbagbọ́. Awọn ohun wọnni ti ọpọlọpọ eniyan n titori rẹ̀ gbé ẹmi wọn tà, ani eyi ti o tilẹ ná wọn ni owo iyebiye lati ni wọn, a pada di ohun ti kò nilaari mọ́. O maa n dabi iwa were loju ẹni ti kò ni igbala pe ki iranşẹ Ọlọrun gbagbe gbogbo ilepa fun ipo giga ayé. Şugbọn ayọ̀ ati ibukun ti Onigbagbọ́ ni kò le şee fi şe akawe awọn ohun asán ayé yii. Ayọ̀ rẹ̀ jẹ eyi ti owo kò le rà. Iyin awọn eniyan ati okiki ayé ki i şe opin ti o n lepa, şugbọn o n lepa lati wu Ẹni ti O pe e lati Ọrun wá.

Ayọ idariji ẹ̀şẹ jẹ́ ọ̀kan ninu ayọ̀ ti o tobi julọ ti ọmọ-eniyan le mọ̀. Gbogbo iran eniyan patapata ni o jọ ni iriri kan naa, eyi si ni pe olukuluku eniyan ni o mọ idalẹbi ẹ̀şẹ. Olukuluku ẹni ti o wà labẹ ẹrù ẹşẹ ni o ni idalẹbi ọkàn fun ẹşẹ paapaa julọ ẹrù naa a di wuwo si i nigba ti Ọlọrun ba rán Ẹmi Mimọ́ ti o n dá ẹ̀şẹ lẹbi. Nigba naa ẹrù wuwo yii a di eyi ti o şoro lati rù; lati ri idariji gbà ki ẹrù yii si bọ́ maa n mu ayọ̀ ti a kò le fi ẹnu şakawe rẹ̀ wá -- ayọ̀ igbala.

### Lilepa Lati Dabi Kristi

Paulu kò ka ara rẹ̀ si ẹni ti o ti dé opin ire-ije rẹ̀ ni ti Igbagbọ́ şugbọn o tẹju mọ́ opin naa şinşin bi akọ okuta ti a sọ si iha Sioni. O n gbagbe awọn ohun ti ẹyin o si n lepa awọn ohun ti i şe ti Ọlọrun. O mọ̀ pe ire-ije oun jẹ eyi ti o logo julọ o si mọ̀ dajudaju pe oun yoo ni ẹ̀kún ayọ̀ nigba ti oun bá ri Jesu ni ojukoju. Ni akoko ọjọ́ ogbó Paulu, o le wo ẹyin ki o si wi pe: "Emi ti jà ija rere, emi ti pari ire-ije mi, emi ti pa igbagbọ́ mọ́: Lati isisiyi lọ a fi ade ododo lelẹ fun mi, ti Oluwa,

onidajọ ododo, yio fifun mi li ọjọ na, ki si iṣe kiki emi nikan, ṣugbọn pẹlu fun gbogbo awọn ti o ti fẹ ifarahàn rẹ̀" (2 Timoteu 4:7, 8). Ni opin ọ̀rọ rẹ̀ si Timoteu gẹgẹ bi ẹri ti o dabi ẹni pe ire-ije naa n lọ si opin. O ti la awọn nnkan wọnyii kọja; ọpọ iṣẹ́ ti o ti ṣe, paṣan, tubu, ewu ọkọ, ewu oju omi, ti awọn ọlọṣa, ewu lati ọdọ awọn keferi, ewu ninu ilu ati ninu aginju. Ebi ati oungbẹ, otutu ati ihoho ni awọn nnkan miiran ti o ti là kọja pẹlu. Nigba ti gbogbo awọn nnkan wọnyii de ba a, oun ka a si ayọ̀ lati jiya nitori ti Kristi; ṣugbọn nisisiyii ti igbesi-ayé rẹ̀ fẹrẹ dopin, laipẹ oun yoo mọ anfaani ti o jẹ lati ji ni aworan Kristi. Nigba naa, ani nigba naa gan an ni ayọ̀ nini igbala rẹ̀ yoo di kikún. Ayọ̀ ti ihin jẹ́ iyanu, irẹpọ nihin si dùn jọjọ, ṣugbọn ayọ̀ ayeraye ṣi n duro de e, bẹẹ naa ni o si n duro de gbogbo awọn wọnni ti o ni ipin ninu Ajinde Kin-in-ni. Nitori ti o mọ eyi bẹẹ, kò ya ni lẹnu pe nigba ti Paulu wà ninu tubu ni Romu o le sọ bayii pe: "Emi nlepa lati de opin ire-ije nì fun ère ìpe giga Ọlọrun ninu Kristi Jesu" (Filippi 3:14).

### Ẹ Maa Yọ̀ Ninu Oluwa

A pa a laṣẹ fun wa lati maa yọ ninu Oluwa. Awọn miiran ka eyi si anfaani ṣugbọn pe ki i ṣe ojuṣe ti a fi dandan lé. Igbagbọ́ ninu Ọlọrun ni o maa n mu ni yọ̀. Kristi, nitori ayọ̀ ti a gbé ka iwaju Rẹ̀, O farada agbelebu. Pẹlu ayọ nla awa n bojuwo ẹyin pe O ti ru awọn ẹ̀ṣẹ wa ni Kalfari. Ayọ̀ ti a gbé ka iwaju Rẹ̀ ni pe ki O le jẹ́ Olugbala wa. Ayọ̀ wa si gbọdọ duro lori pe a wà ninu Oluwa. Igbesi-ayé Onigbagbọ́ jẹ́ ti iṣẹgun ati alaafia. Onigbagbọ́ si ti gbé awọn ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ru Jesu; o ti fi gbogbo aniyan rẹ̀ sabẹ abojuto Ọlọrun; o ti gbé gbogbo ifoya rẹ̀ ka ori awọn ileri Ọlọrun, ati ni iru ipo ibukun bayii kò ni ayè fun ohun miiran bi ko ṣe ayọ̀ ninu ọkàn rẹ̀. Ninu ẹdùn ọkàn rẹ̀ fun awọn ti a kò i ti i gbala o gbagbọ pe Ọlọrun ti o gba oun là yoo ṣe bakan naa fun awọn olufẹ rẹ̀. Oun kò le bá wọn ru ẹrù awọn ẹ̀ṣẹ wọn, bẹẹni kò si le ba wọn ronu piwada; ṣugbọn bi o ti n gbadura pẹlu igbagbọ́, o n yọ̀ pe oun le gbẹkẹle Ọlọrun ati Ọrọ Rẹ̀.

### Iwọntunwọnsi ati Igbẹkẹle

Oluwa n fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ maa ṣe nnkan ni iwọntunwọnsi. A kò gbọdọ gbọjẹgẹ, bẹẹni a kò gbọdọ gba ohunkohun ti Ọrọ Ọlọrun dalẹbi láàyè; ṣugbọn a gbọdọ ranti bakan naa pe Ọlọrun ki i ṣe olupilẹṣẹ rudurudu tabi aṣerege. Awọn ẹlẹsin miiran wà ti wọn funka mọ́ koko kan ninu Ọrọ Ọlọrun ti wọn si ti fun un ni itumọ ti o yapa tobẹẹ ti o sọ ẹ̀kọ́ wọn di alainilaari ati eyi ti o lodi si Iwe Mimọ́. A gbọdọ fi Iwe Mimọ́ tumọ Iwe Mimọ́ ki i si ṣe pe ki a dá ẹsẹ kan ṣoṣo yọ ki a si gbé gbogbo igbagbọ́ wa le ori ohun ti ẹsẹ kan ṣoṣo ti a dá yà sọtọ naa fi kọ́ ni. Bibeli kò tako ara rẹ̀ rara. A gbọdọ kọ́ gbogbo Bibeli ki a si gba gbogbo rẹ̀ gbọ́ ki a ba le pin ọ̀rọ otitọ naa bi o ti yẹ. A kà ninu Johannu 7:17 "Bi ẹnikẹni ba fẹ lati ṣe ifẹ rẹ̀, yio mọ̀ niti ẹ̀kọ́ na, bi iba ṣe ti Ọlọrun, tabi bi emi ba nsọ ti ara mi." Ọpọlọpọ ẹ̀kọ́ èké ni a ti ti ọwọ awọn ti o kọ̀ lati ṣe ifẹ Ọlọrun dá silẹ. Lati bo ẹ̀ṣẹ wọn mọlẹ wọn a fun Ọrọ Ọlọrun ni itumọ tiwọn wọn a si gbé ẹ̀kọ́ tiwọn kalẹ. Ọlọrun sọ nipa Israẹli afasẹyin pe "Nitori awọn enia mi ṣe ibi meji: nwọn fi Emi, isun omi-iye silẹ, nwọn si wà kanga omi fun ara wọn, kanga fifọ́ ti kò le da omi duro" (Jeremiah 2:13).

Ọlọrun fẹ ki awọn eniyan Oun gbẹkẹle Oun. Bi wọn ba ṣe bẹẹ, wọn ki yoo ṣaniyan rekọja. Itumọ eyi ni pe wọn ki yoo jẹ ki aniyan wọn ki o jọba lori ọkàn wọn. Bi a ba mu gbogbo ifẹ ọkàn wa tọ Oluwa wá ti a si gbadura pẹlu idupẹ, gbogbo aniyan ọkàn wa yoo fò lọ. Nigba ti a ba fi igbagbọ́ gbadura si Ọlọrun, a ni igbẹkẹle ninu Rẹ̀ pe yoo dahun adura wa, yoo si ṣe ohun wọnni ti a bèere lọwọ Rẹ̀ bi o ba ṣe gẹgẹ bi ifẹ Rẹ̀. Gbogbo adura wa ati ifẹ wa duro le bi o ba ṣe ifẹ Rẹ̀ lori, nitori pe kò si ọmọ Ọlọrun kan ti o fẹ ki ifẹ ti oun bori ti Ọlọrun. Jesu fi apẹẹrẹ lelẹ fun wa ninu adura Rẹ̀ ninu Ọgba Gẹtsemane nigba ti o wi pe: "Baba mi, bi o ba le ṣe, jẹ ki ago yi ki o kọja kuro lori mi, ṣugbọn ki má ṣe bi emi ti nfẹ, bikoṣe bi iwọ ti nfẹ" (Matteu 26:39).

### Awọn Ero Ọkàn Wa

Ọlọrun ti kọ́ wa ninu ẹ̀kọ́ yii pe a gbọdọ ṣakoso awọn ero ọkàn wa. Ireti kan ṣoṣo fun igbala wà lori itoye Ẹjẹ Jesu ti a ta silẹ. A ri i pe ki i ṣe nipa erò ọkàn wa ni a fi gbà wa là, ṣugbọn a pa a laṣẹ fun wa lati maa ronu lori awọn ohun ti o tọ́. Eniyan kọkọ gbọdọ ronu ni ọna ti o tọ́ ki o to le gbadura ni ọ̀na ti yoo tọ̀nà. A kò le sọ ara ẹni di olododo nipa ero inu wa, ṣugbọn nitori pe a ti sọ wa di olododo nipa ododo ti Kristi o ṣeeṣe fun wa lati gbọran si gbogbo aṣẹ Ọlọrun ati lati le maa ronú lori awọn nnkan wọnni ti i ṣe ootọ, ti i ṣe ọ̀wọ, ti i ṣe titọ́, ti i ṣe mimọ́, ti i ṣe fifẹ, ti o ni ihinrere, ati ti o ni iyin.

Gbogbo wa ni a mọ awọn eniyan ti wọn maa n ri abuku kan tọkasi ninu olukuluku eniyan. A ko gbọdọ rò pe idajọ iru ẹni bẹẹ ti ọdọ Oluwa wá. A kilọ fun wa pe ki a maa gbadura fun awọn ti o ṣiṣe ki a si maa ṣe iranlọwọ fun awọn ti o ṣubu (lati dide). A mọ̀ pe iwa ṣiṣe atako ati ifisun awọn ti o dẹṣẹ kò fihan pe iru ọkàn bẹẹ jẹ́ eyi ti o kún fun ẹ̀bẹ ti o si n ké pe Ọlọrun lati ṣaanu fun awọn wọnni ti o ti ṣẹ̀. A kò gbọdọ maa tọka si iṣẹ buburu wọnni ti eṣu ti ṣe. Ninu gbogbo ayidayida ayé, àfo maa n ṣi silẹ lati ri i pe ohun gbogbo ni o n ṣiṣẹ pọ̀ si rere fun awọn ti o fẹ́ Ọlọrun (Romu 8:28). Ki i ṣe pe ki a bo ẹ̀ṣẹ mọlẹ lọna pe ki a pa ohùn dà ki a si maa pe ibi ni rere, ṣugbọn ninu didá ẹ̀ṣẹ lẹbi ni igbesi-ayé ẹlomiran, o ṣeeṣe fun ni lati ni idakọro ọkàn ti igbagbọ́ ni inu otitọ yii pe ọ̀ràn rẹ̀ kò i ti kọja oore-ọfẹ irapada ati pe Ọlọrun ṣi fẹran rẹ̀ sibẹ ati pe yoo fi ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ji i bi o bá ronupiwada. Alabukún-fun ni ẹni naa ti o gbẹkẹle Oluwa ti o si n yọ̀ ninu aanu Rẹ̀. "Iwọ o pa a mọ li alafia pipé, ọkàn ẹniti o simi le ọ: nitoriti o gbẹkẹle ọ" (Isaiah 26:3).

## Iṣẹgun Ninu Ipokipo

Ayọ̀ ti Paulu n yọ̀ ninu Ihinrere ki i ṣe nitori pe o wà ni ipo irọra. Ebi ti pa a o si ti jẹ ajẹyó. Otutu ti mu un, a si ti mu un lara gbona. O yọ̀ pe awọn Onigbagbọ́ ara Filippi ti pese fun aini rẹ̀ nitori ere ti wọn yoo gbà fun ṣiṣe bẹẹ (Filippi 4:17). Bi o ba ṣe pe awọn ohun ti o n ṣẹlẹ nipa ti ara ni awọn Onigbagbọ́ gbẹkẹle fun idaniloju pe ibukun Ọlọrun wà fun wọn, ọpọlọpọ eniyan ni ki yoo ni ireti. Pupọ ninu awọn ti wọn ṣe alaini julọ ninu ayé ni wọn ti ni iṣẹgun ti o yanilẹnu pupọ julọ nipa ti ẹmi. Pupọ awọn ti wọn ti ni ọpọlọpọ ini ayé nigba kan ri ni wọn tun ti di alaini ohunkohun, ṣugbọn eyi kò gba igbagbọ́ ti wọn ni ninu Ọlọrun lọwọ wọn. Ni ọpọ igba ni eyi kuku maa n mu ki oungbẹ ti ẹmi pọ̀ si i ati ki wọn si ni igbẹkẹle ti o daju pe alaafia pipé wà ninu ọkàn wọn.

Paulu mọ̀ pe agbara oun wà ninu Kristi. Ẹru kò ba a fun iṣẹ ti o wà lọwọ rẹ̀ nigba naa tabi nitori eyi ti yoo doju kọ ọ lọjọ iwaju, nitori pe o di ileri yii mu pe gẹgẹ bi ọjọ rẹ̀ bẹẹ gẹgẹ ni agbara rẹ̀ yoo rí. Ẹnikan ti sọ pe oun ni "oore-ọfẹ ti n bẹ laaye" o si mọ dajudaju pe nigba ti wakati ikú ba dé Ọlọrun yoo fun oun ni oore-ọfẹ ti o tó fun oun lati rekọja lọ.

### AWỌN IBEERE

1 Awọn wo ni a n tọka si gẹgẹ bi onila nipa ti ẹmi?

2 Ki ni awọn ohun ti Paulu kà si òfò nitori ti Ihinrere?

3 Ki ni ohun pataki ti o leke ọkàn Paulu lati ní?

4 Njẹ Paulu ka ara rẹ̀ si ẹni ti o ti dé opin ire-ije naa? Ki ni o si ṣe nipa rẹ̀?

5 Ki ni ẹri ti ode-ara pe Oluwa wà ninu ọkàn?

6 Ki ni wọn ni lati maa ronu lé lori?

7 Ki ni wọn ni lati ṣe nipa aniyan wọn gbogbo?

8 Iru iha wo ni wọn gbọdọ kọ si iwà aṣerege ati àṣa?

9 Ki ni Paulu ti kọ́ lati maa ṣe ni ipokipo ti o bá wà?

10 Nibo ni Paulu sọ pe agbára oun ti wá?